# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà.

**Oṣù Kárùn, Ọdún 2026**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2026**

**1. Ẹ̀nyin olùkórè nín'oko!**
T'árẹ̀ fẹ́rẹ̀ mú tán;
Ẹ rọ́jú dúró de Olúwa,
Y'Ó s'agbára dọ̀tun.

Àwọn tó dúró d'Olúwa
Y'ó s'agbára wọn d'ọ̀tun,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò bí ìdì,
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀,
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n.

2. Nígbà àrẹ́ àt'irẹ̀wẹ̀sí,
À ngb'ọkàn wa sí Ọ;
Lẹ́yìn t'agba Olùgbàlá gbọ́,
Kí l'a ó tún bẹ̀rù?

3. Ẹ yọ̀! Ó mbá wa gbé lọ́jọjọ́,
Àní títí d'ópin!
Wòkè! ẹ sì ma tẹ̀sìwájú
Y'ó fùn nyín l'ágbára!

1. **Ẹ dide, ọmọ ìgbàlà**

Ẹ̀yin t'ẹ fẹ́ Olúwa;
Dìde, ìlú alágbára
Kí ọ̀tá tó dé Síòn.

F'agbára rẹ kọrin kíkan,
Bí ìró omi òkun;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ.

2. Ẹgbẹ́ mímọ́ ti ìgbanì

Tí wọ́n ti nrin ọ̀nà yí;
W'àsíá wọn t'ó nfẹ́ lẹ́lẹ̀
A ṣẹ́gun nípa Krístì.

3. A ti gbé 'kú mì ní 'ṣẹ́gun,

Ìyè wa mbẹ n'nú Krístì;
L'ọ́jọ́ 'farahàn Olúwa
A ó hó ìhó ayọ́.

4. Láìpẹ́ aó dé'bi ìtẹ́ Rẹ̀,

A ó sì mọ Ọba Ògo,
Níbẹ̀ aó kè, Kábíyèsí"
Gbogbo wa y'ó gba èrè.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ayọ̀ ìkà lórí ayé mi yóò di ibànújẹ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Ìkórajọ̀pọ̀ àwọn àgbà ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi yóò wólulẹ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti ṣe ìdíwọ́ fún ìfarahàn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ògo ayànmọ́ mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo iṣẹ́ àwọn ènìyàn ìkà, tó n mú ìlọ́ra bá ìtẹ̀síwájú mi yóò tapadà lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo àṣeparí ìpinnu búburú òkùnkùn fún ayànmọ́ mi yóò kú nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ifìmọ̀ṣọ̀kan òkùnkùn, láti jẹ́ kí n dìde, kí n tún ṣubú, òní lòpin rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìwà-ìkà ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti dá alàjá ètò-ìṣúná mi dúró, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Orin Dáfídì 11:6** Lórí ènìyàn búburú ni yóò rọ̀jò, ẹyìn gbígbóná àti imí-ọjọ́ àti ijì gbígbóná: èyí ni ìpín ago wọn.

**Orin Dáfídì 28:4** Fi fún wọn gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ wọn, àti gẹ́gẹ́ bí ìwà búburú ètè wọn, fi fún wọn nípa iṣẹ́ ọwọ́ wọn, fi èrè wọn fún wọn.

**Òwe 16:4** Olúwa ti ṣe ohun gbogbo fún ìpinnu rẹ̀: nítòtọ́, àwọn ènìyàn búburú fún ọjọ́ ibi.

**Orin Dáfídì 58:10** Olódodo yóò yọ̀ nígbàtí ó bá rí ẹ̀san nà: yóò sì wẹ ẹsẹ̀ rẹ̀ nínú ẹ̀jẹ̀ àwọn ènìyàn búburú.

**Orin Dáfídì 91:8** Kíkí ojú rẹ ní ìwọ ó ma fi ri, tí ó sì ma fi wo èrè àwọn ènìyàn búburú.

**Orin Dáfídì 59:5** Nítorínà Ìwọ, Olúwa, Ọlọ́run àwọn ọmọ-ogun, Ọlọ́run Ísráẹ̀lì, jí láti bẹ gbogbo àwọn kefèrí wò; máṣe ṣànú fún olùrékọjá búburú wọnnì.

**Ìsáíàh 13:11** Èmi ó sì bẹ ibi wò lára ayé, àti àiṣedédé lárá àwọn ènìyàn búburú, èmi ó sì mú kí ìgbéraga àwọn agbéraga kí ó mọ, èmi ó sì mú ìgbéraga àwọn alágbára rẹ̀ sílẹ̀.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹrù ìkà ìyówù tí wọ́n gbé sórí ayànmọ́ mi, tapadà báyìí, ní orúkọ Jésù.

4. Gbogbo ẹrù itìjú tí wọ́n dì rù mí l'ọ́nà aìtọ́, tapadà, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ẹrù tí ó yẹ kí ó dí ìtẹ̀síwájú mi lọ́wọ́, sọ ìgbámú rẹ nù, ní orúkọ Jésù.
6. Gẹ́gẹ́ bí Ọ̀rọ̀ Olúwa, ibi yóò padà sọ́dọ̀ àwọn ìkà, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo iṣẹ́ ìwà-ìkà tí wọ́n ṣe lòdì sí orí mi, tapadà báyìí, ní orúkọ Jésù.